NYC Consumer Affairs
Bill de Blasio
Mayor
Lorelei Salas
Commissioner

# ÀKÍYÈSÍ ÀWỌN ẸTỌ́ ÒṢÌṢẸ́
## FÚN ÀWỌN OLÙTỌ́JÚ ỌMỌ, OLÙTỌ́JÚ ILÉ, ÀTI ÀWỌN ÒṢÌṢẸ́ ILÉ MÍRÀN

Lábẹ́ New York City's Earned Safe and Sick Time Act (Paid Safe and Sick Leave Law), àwọn òṣìṣẹ́ abẹ́lé ní ẹ̀tọ́ sí àkókò ìsinmi ìgbà àìsàn àti ààbò. Lọ sí nyc.gov/PaidSickLeave láti kọ́ síi nípa òfin náà.

**Àwọn òṣìṣẹ́ ilé tí ń ṣiṣẹ́ tààrà fún àwọn agbanisiṣẹ́ ilé kọ̀kan gbọ́dọ̀ gba àkíyèsí tí a kọsílẹ̀ yìí láti ọ̀dọ̀ agbanisiṣẹ́ wọn nígbàtí wọ́n bá bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ tàbí ní Ọjọ́ 4 Oṣù kẹfà, ọdún 2018, èyíkéyìí tó bá kọ́ wáyé.**

### O NÍ ẸTỌ́ SÍ ÌGBÀ ÌSINMI ÀBÒ, èyí tí o le lò láti wá ìrànlọ́wọ́ tabí ṣe ohun àbò míràn tí ìwọ tàbí mọ̀lẹ́bí rẹ bá ní ìrírí ìhàlẹ̀ tàbí ìṣe ìwà ipá abẹ́lé tàbí ìfọwọ́pani lára tí o kò fẹ́ fún ìbálòpọ̀, àyọjúràn, tàbí ìfipá tani sókè òkun.

### O NÍ ẸTỌ́ SÍ ÌGBÀ ÌSINMI ÀBÒ, èyí tí o le lò fún ìtọ́jú ara àrẹ tàbí ti mọ̀lẹ́bí kan.

#### ÀWỌN ÒṢÌṢẸ́ ABẸ́LÉ TÓ NÍ ÀÀBÒ/ÈYÍ TÍ KÒ NÍ ÀÀBÒ ÒFIN:

| Èyí tó ní ààbò | Èyí tí kò ní ààbò |
|---|---|
| O *jẹ́* òṣìṣẹ́ abẹ́lé tó ní ààbò òfin tí a bá gbà ọ́ síṣẹ́ tààrà nípasẹ̀ ẹbí tàbí mọ̀lẹ́bí kan o sì:<br>• Tọ́jú àwọn ọmọdé<br>• Pèsè ìtọ́jú fún àwọn àgbàlagbà, aláìsàn, abarapá, tàbí ẹnití ara rẹ̀ yá.<br>• Ṣe àwọn iṣẹ́ tó jọmọ́ ìtọ́jú ilé bíi iná dídá àti pípalẹ̀mọ́ | O *kò* jẹ́ "òṣìṣẹ́ abẹ́lé" lábẹ́ òfin àti, nítorí náà, o kò ní ààbò tí o bá ń ṣe àwọn iṣẹ́ ti a ṣàlàyé ní abala 1 fún mọ̀lẹ́bí kan nípasẹ̀ aṣoju agbanisíṣẹ́.<br>Àwọn òṣìṣẹ́ tí a gbà nípasẹ̀ aṣojú le ní tó wákàtí 40 tí ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbò tí a sanwó fún nípasẹ̀ òṣìṣẹ́ lábẹ́ òfin. Lọ sí nyc.gov/PaidSickLeave láti kọ́ síi nípa òfin náà. A le ṣàyẹ̀wò rẹ bíi "òṣìṣẹ́ abẹ́lé" fún àwọn èrè ìdí ti òfin ilẹ̀ New York kí o sì gba àfikún àbò. |

#### IYE ÌGBÀ ÌSINMI ÀÌSÀN ÀTI ÀBÒ:

- Lẹ́yin ọdún kan tí a gbà ọ́ sí iṣẹ́, agbanisíṣẹ́ rẹ gbọ́dọ̀ pèsè ọjọ́ méjì ti ìgbà ìsinmi àìsàn àti àbò tí a sanwó fún. Ìgbà ìsinmi ìlú jẹ́ àfikún sí ọjọ́ mẹ́ta ti ìsinmi tí a sanwó fún tí o le lẹ́tọ́ sí lábẹ́ Òfin New York State. Fún àlàyé síwájú síi nípa àwọn ẹ̀tọ́ rẹ lábẹ́ Òfin ìjọba, lọ sí labor.ny.gov kí o sì wá "Àwọn Òṣìṣẹ́ Abẹ́lé' Àwọn Ẹ̀tọ́ Òfin."

#### DÉÈTÌ TÍ ÌGBÀ ÌSINMI ÀÌSÀN ÀTI ÀBÒ WÀ NÍLẸ̀ FÚN LÍLÒ:

- O le bẹ̀rẹ̀ lílò ìgbà ìsinmi àìsàn ní Ọjọ́ 1 Oṣù kẹ̀rin, Ọdún 2015 tàbí ọdún kan lẹ́yìn tí o bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́, èyíkéyìí tó bá yá.
- O le bẹ̀rẹ̀ lílò ìgbà ìsinmi ààbò ní Ọjọ́ 5 Oṣù kàrún, Ọdún 2018 tàbí ọdún kan lẹ́yìn tí o bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́, èyíkéyìí tó bá yá.

#### ÀWỌN ÌDÍ TI A GBÀ LÁTI LO ÌGBÀ ÌSINMI ÀÌSÀN ÀTI ÀBÒ:
O le lo ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbò láti gba ìsinmi níbi iṣẹ́ nígbàtí:

- O ní àìsàn ọpọlọ tàbí ara, ìpalára, tàbí ipò àìlera; o ní láti ṣe àyẹ̀wò ìtọ́jú ìlera, ìtọ́jú ara, ìtọ́jú àìsàn tí àìsàn ọpọlọ tàbí ara rẹ, ìpalára, tàbí ipò; o ní láti gba ìtọ́jú ara tí ń dènà àìsàn.
- O gbọ́dọ̀ tọ́jú mọ̀lẹ́bí kan tó nílò àyẹ̀wò ìtọ́jú ara, ìtọ́jú ìlera, tàbí tó nílò ìtọ́jú ara tàbí àìsàn ọpọlọ, ìpála, tàbí ipò ìlera, tàbí ẹni tó nílò ìtọ́jú tí ń dènà aìsàn.
- Òwò agbanisíṣẹ́ rẹ dópin nítorí pàjáwìrì ìlera gbogbogbò tàbí o ní láti tọ́jú ọmọ kan èyítí ilé-ìwé rẹ̀ tàbí olùpèsè ìtọ́jú rẹ̀ kò ṣiṣẹ́ nítorí pàjáwìrì ìlera gbogbogbò.
- Ìwọ tàbí mọ̀lẹ́bí kan le ní ìrírí ìwà ipá abẹ́lé ti ìhàlẹ̀ tàbí ìṣe tàbí ìfọwọ́pa lárati ìbálòpọ̀, àyọjúràn, tàbí fífí ipá mú ni lọ òkè òkun o sì ní láti gbé ìgbésẹ̀ tó ṣe pàtàkì láti dá ààbò ati ìlera ọrọ̀-ajé tàbí ìròrnú tàbí ti ara padà ti ìwọ tàbí àwọn mọ̀lẹ́bí tàbí láti dá ààbò bo awọn tí ṣe pẹ̀lú rẹ tàbí tí ń bá ọ ṣiṣẹ́, pẹ̀lú láti:
    - Gba àwọn iṣẹ́láti ilé ààbo ìwà ipá abẹ́le, ibi àrélù ìwà àfipá bánilò, tàbí ètò àwọn iṣẹ́ míràn.
    - Kópa nínú ètò àbò, ló síbò míràn, tàbí gbé àwọn ìgbésẹ̀ míràn láti tọ́jú ààbò rẹ tàbí ti mọ̀lẹ́bí rẹ, pẹ̀lú fífí orúkọ ọmọ sílẹ̀ ní ilé-ìwé titun kan.
    - Bá agbẹjọ́rò kan sọ̀rọ̀ tàbi olùpèsè iṣẹ́ ìgbàlódé láti gba àlàyé àti ìmọ̀ràn tó jọmọ́ gbígba ọmọ sọ́dọ́; àbẹ̀wò; àwọn ìṣòro ìgbéyàwó; àwọn àṣẹ àbo; ọ̀rọ̀ ìrìn-àjò; ilé gbígbé; ẹlẹ́yàmẹ̀yà ní ibi iṣẹ́; ilé gbígbé tàbí kirẹditi aṣàmúlò.
    - Jábọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ abẹ́lé kan pẹ̀lú àgbófinró tàbí ṣe ìpàdé pẹ̀lú ilé-iṣẹ́ agbẹjọ́rò ti agbègbè kan.

Síwájú síi >

### ÀWỌN MỌ̀LẸ́BÍ:

Òfin náà ṣètò àwọn ènìyan wọ̀nyí bíi "àwọn mọ̀lẹ́bí:"

- Ẹnikẹ́ni tí ìṣepọ̀ rẹ̀ pẹ̀lú agbanisíṣẹ́ bá dàbí ti ẹbí
- Ọmọ (tí a bí, tí a gbàtọ́, tàbí tí a fi ṣe ọmọ; olùtọ́jú tó bá òfin mu; ọmọ agbanisíṣẹ́ tí ń dúró *ibíí òbí*)
- Ọmọ-ọmọ
- Olólùfẹ́
- Alájọṣe Abẹ́lé
- Òbí
- Obí àgbà
- Ọmọ tàbí Òbí olólùfẹ́ agbanisíṣẹ́ tàbí alájọṣe abẹ́lé
- Ọmọ ìyá (pẹ̀lú ìbátan, àgbàtọ́, tàbí ti ìyá míràn)
- Ẹlòmíràn tó bá agbanisíṣẹ́ tan nípasẹ̀ ẹ̀jẹ̀

### ÀKÍYÈSÍ ṢÁÁJÚ ÀKÓKÒ:

Tí a bá ti rò èyí tẹ́lẹ̀, agbanisíṣẹ́ rẹ le nílò àkíyèsí tí ó tó ọjọ́ méjè ti èrò rẹ láti lo ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbò. Tí a kò bá ro eyi tẹ́lẹ̀, agbanisíṣẹ́ rẹ le nílò kí o fún òhun ní àkíyèsí ní kété tó bá ti dájú.

### ÌWÉ ÀKỌSÍLẸ̀:

Agbanisíṣẹ́ rẹ nílò ìwé àkọsílẹ̀ ti o bá lò ju ọjọ́ mẹ́ta ti ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbo lọ nígbà kannáà. Òfin Ìgbà Ìsinmi Àìsàn àti Ààbò Tí A Sanwó fún dèna kí àwọn agbanisíṣẹ́ máa bèrè lọ́wọ́ olùpèsè ìtọ́jú ìlera ìdí fún ìgbà ìsinmi àìsàn tabí bèrè ìwé àkọsílẹ̀ fún ìgbà ìsinmi ti ààbò láti sọ ní pàtó ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé tí èyíkéyìí ìṣe tàbí ìhàlẹ̀ ti ìwà ipá abẹ́lé tàbí ìfọwọ́pani lára ti ìbálòpọ̀, àyọjúràn, tàbí ìfipa mu ni lọ sí òkè òkun. Àwọn òfin náà le bèrè àfihàn.

## O NÍ Ẹ̀TỌ́ LÁTI BỌ́ LỌ́WỌ́ Ẹ̀SAN LÁTI ỌWỌ́ AGBANISÍṢẸ́ RẸ FÚN LÍLO ÌGBÀ ÌSINMI ÀÌSÀN ÀTI ÀÀBÒ.

Agbanisíṣẹ́ rẹ kò le gbẹ̀san lára rẹ fún:

- Bíbèrè àti lílo ìgbà ìsinmi àìsàn àti àbò.
- Ìfisùn ẹ̀dùn ọkàn kan fún àwọn ìwà ìrúfin pẹ̀lú DCA.
- Bíbá ẹnikẹ́ni sọ̀rọ̀, pẹ̀lú àwọn alájọ sìṣẹ́, nípa èyíkéyìí ìrúfin.
- Kíkópa nínú ọ̀ràn ní ilé-ẹjọ́ nípa ìrúfin tí a fisùn.
- Sísọfún ẹlòmíràn nípa ti àwọn ẹ̀tọ́ tó le ní.

Ẹ̀san pẹ̀lú èyíkéyìí ìhàlẹ̀, ìfìyà jẹ ẹni, ìgbaṣẹ́ lọ́wọ́ ẹni, ìgboyè lọ́wọ́ ẹni, ìdádúró díẹ̀, tàbí ìdínkù nínú wákàtí iṣẹ́ rẹ, tàbí èyíkéyií iṣe iṣẹ́ tó lágbára tí a ṣe sí ọ fún àmúlò tàbí ìgbìyànjú láti ṣàmúlò ẹ̀tọ́ rẹ lábẹ́ òfin.

## O NÍ Ẹ̀TỌ́ LÁTI SỌ Ẹ̀DÙN ỌKÀN RẸ.

O le sọ ẹ̀dùn ọkàn rẹ pẹ̀lú DCA. Láti gba fọ́ọ̀mù ẹ̀dùn ọkàn, lọ sórí ayélujára sí **nyc.gov/PaidSickLeave** tabí kàn sí 311 (212-NEW-YORK lóde NYC).

DCA yóò ṣe ìtọpinpin wọn yóò sì gbìyànjú láti tán ẹ̀dùn ọkàn náà. DCA yóò fi ìdánimọ̀ rẹ pamọ́ àyàfi tí a bá ní láti fihàn láti ṣe ìtọpinpin, yanjú ẹ̀dùn ọkàn náà, tàbí tó nílò lábẹ́ òfin.

**Tọ́jú ẹ̀dà àkíyèsí yìí àti gbogbo ìwé àkọsílẹ̀ tó ṣàfihàn iye ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbo tí o ní tí o sì lò.**

**Àkíyèsí: Òfin Àkókò Àìsàn àti Ààbò Tí O Gbà ṣètò àmúyẹ tó kéréjù fún ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbò. Àwọn òfin ìgbà ìsinmi tí agbanisíṣẹ́ rẹ le ti ṣebámu tàbí kọjá àwọn àmúyẹ ti òfin nà.**

O ní ẹ̀tọ́ kan láti gba àkíyèsí yìí ní Èdè Gẹ̀ẹ́sì àti, tó bá wa ní ojúlé wẹ́ẹ̀bù ti DCA, èdè àkọ́kọ́ rẹ.

Fún àlàyé síwájú síi, pẹ̀lú Àwọn Ìbéèrè Tí A Ń Sábà Bèrè, lọ sí **nyc.gov/PaidSickLeave** tàbí pe **311** kí o sì bèrè fún àlàyé nípa Ìgbà Ìsinmi Àìsàn àti Àbò Tí A Ń Sanwó Fún.